# IṢẸ IRIJU TOOTỌ

**1 Timoteu 6:1, 2; Efesu 6:5-9; Romu 13:1-8**

**ẸKỌ 358 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ohunkohun ti ẹnyin ba nṣe, ẹ mã fi tọkàntọkàn ṣe e, gẹgẹ bi fun OLUWA, ki si iṣe fun enia" (Kolosse 3:23).**

**I Ojuṣe Awọn Oṣiṣẹ si Awọn Ọga wọn**

1 Wọn ni lati bu ọla fun awọn ti o gbà wọn si iṣẹ́, 1 Timoteu 6:1, 2; Kolosse 3:22; Titu 2:9, 10; 1 Peteru 2:18

2 Wọn ni lati ṣe iṣẹ́ wọn gẹgẹ bi fun Oluwa, Efesu 6:5-8; Kolosse 3:23

**II Imọran fun Awọn Agbanisiṣẹ**

1 Wọn ni lati fi ọ̀wọ̀ bá awọn oṣiṣẹ wọn lò, Efesu 6:9

2 Wọn ni lati san iye owó ti o tọ́ fun wọn, Kolosse 4:1; Jakọbu 5:4

**III Ihà ti Onigbagbọ́ Gbọdọ kọ si Ofin**

1 "Awọn alaṣẹ ti o si wà, lati ọdọ Ọlọrun li a ti làna rẹ̀ wá", Romu 13:1, 2; Owe 8:15; Daniẹli 4:32

2 Awọn ti o ba ṣe rere kò le bẹru idajọ ofin, Romu 13:3, 4

3 Awọn Onigbagbọ́ ni lati gbọran si ofin, Romu 13:5-7; 1 Peteru 2:13, 14; Marku 12:17

## ALAYE

### A Dán Isin Kristi Wò

Nigba miiran a le pin ofin Ọlọrun si ipa meji – eyi ti o jẹ́ iṣẹ́ wa si Ọlọrun ati eyi ti i ṣe iṣẹ wa si ọmọnikeji wa. A ko le sin Ọlọrun lai naani ọmọnikeji wa – aladugbo wa, ọmọ-ọdọ wa, ọga wa.

Orukọ Ọlọrun, ati ẹkọ Rẹ́ a maa jẹ́ ayinlogo nipa iwa awọn ọmọlẹyin Rẹ̀ tootọ. Ayé a maa tete ri apẹẹrẹ kánkán ju fifi ilana ẹkọ lelẹ lọ. "Ẹnyin ni iwe wa, ti a ti kọ si wa li ọkàn, ti gbogbo enia ti mọ̀, ti nwọn si ti kà" (2 Kọrinti 3:2). A maa n sọ ẹkọ Ọrọ Ọlọrun di titobi nipa awọn ti n gbé igbesi-ayé iwa-bi-Ọlọrun, ṣugbọn a maa n sọ blasfeme si I nitori ti awọn ti wọn n pe orukọ Rẹ̀, ṣugbọn ti wọn kò gbé igbesi-ayé wọn gẹgẹ bi Ọrọ Rẹ̀. Nigba miiran a maa n sọ nipa eniyan pe "Onigbagbọ tootọ ni o n lọ nì." Bẹẹ ni a si maa n gbọ nipa ẹlomiran pe, "Bi o ba ṣe pe isin Kristi ni eyi, emi kò ni nnkankan fi ṣe."

O fẹrẹ jẹ́ pe kò si ibi ti a tun le ṣe akiyesi ẹsin igbagbọ́ ju ninu iwa Onigbagbọ́ lẹnu iṣẹ́ rẹ̀. Awọn alabojuto eto-iṣẹ́ ti lọ jinna ni ṣiṣe atunṣe anfaani eto-iṣẹ fun awọn oṣiṣẹ ṣugbọn ni igba pupọ ni wọn ti ṣe alainaani eto ilana Igbagbọ́ ki wọn ba le ṣe ohun ti wọn n fẹ́. Onigbagbọ́ ti o n ṣiṣẹ ni lati kiyesara ki o máṣe afarawe iṣe aiwa-bi-Ọlọrun awọn ẹlẹṣẹ ninu iṣesi rẹ̀ si awọn ti o gba a si iṣẹ́.

"Ki gbogbo awọn ti iṣe ẹrú labẹ irú mã ka awọn oluwa ti o ni wọn yẹ si ọla gbogbo, ki a má bã sọrọ-odi si orukọ Ọlọrun ati ẹkọ́ rẹ̀" (1 Timoteu 6:1). Ikilọ yii wà fun awọn ti a gbà si iṣẹ lọjọ oni gẹgẹ bi o ti wà fun ẹrú ti akoko Paulu. Bawo ni eniyan ṣe le ka ọga rẹ̀ yẹ si ọla ti kò si ni mura lati tẹ́ ọga naa lọrun? "Gba awọn ọmọ-ọdọ niyanju lati mãṣe ohun ti o wu wọn ninu ohun gbogbo; ki nwọn ki o má gbó wọn lohun" (Titu 2:9). Ọlọrun n fẹ ki awọn ọmọ-ọdọ maa tẹriba fun awọn ọga wọn. "Ẹnyin ọmọ-ọ̀dọ, ẹ mã tẹriba fun awọn oluwa nyin pẹlu ibẹru gbogbo; ki iṣe fun awọn ẹni rere ati oniwa tutu nikan, ṣugbọn fun awọn onrorò pẹlu" (1 Peteru 2:18). Eyi jẹ́ ki a mọ̀ pe a kò gbọdọ má tẹ́ ọga ibiṣẹ wa lọrun nitori pe o jẹ́ ẹlẹṣẹ tabi eniyan buburu; a kàn án nipa fun wa lati tẹriba fun awọn ọga onikanra pẹlu. Eyi nì ni pe fun awọn ti ki i gbọ́ alaye tabi amọran, fun awọn ti i maa mọọmọ ṣe ibi ati agidi.

Niwọn igba ti a kò ba palaṣẹ fun wa lati ṣe ibi, a gbọdọ fun ọga ibi iṣẹ wa ni igbọran pipe. "Ki nwọn ki o má gbó wọn lohun" ni pe ki a máṣe jà wọn niyan bi kò ṣe ki a gba aṣẹ awọn olori wa.

### Iṣẹ́ ti a Ṣe fun Kristi

Onigbagbọ́ ti n ṣiṣẹ ni lati ṣe iṣẹ́ oojọ rẹ̀ gẹgẹ bi "si Kristi; ki iṣe ti arojuṣe bi awọn ti nwu enia; ṣugbọn gẹgẹ bi awọn ẹrú Kristi, ẹ mãṣe ifẹ Ọlọrun lati inu wá; ẹ mã fi inu rere sin bi si Oluwa, ki si iṣe si enia: (Efesu 6:5-7). "Arojuṣe" jẹ́ ọrọ ti o ṣe apejuwe daradara ọ̀na ti awọn ẹlomiran n gba ṣe iṣẹ́. Wọn maa n ṣọra gidigidi lati ri i pe wọn dá ọwọ́ le iṣẹ́ kan lati ṣe nigba ti alabojuto iṣẹ́ bá wà ni tosi, ṣugbọn gẹrẹ ti alabojuto iṣẹ́ naa ba ti lọ wọn a dẹ ọwọ́ iṣẹ́ wọn, wọn a bẹrẹsi isinmi, wọn a si maa fi akoko wọn ṣofo. Nigba ti alabojuto iṣẹ ba tun pada bọ̀, lẹsẹ kan naa wọn a si tun bẹrẹ si maa lọ firifiri. Awọn ẹlomiran ti kò jẹ́ ronu ati jale rara a maa fi akoko eyi ti onişẹ ti sanwo rẹ́ fun wọn ṣofo.

“Arojuṣe” tun ṣe apejuwe irú awọn ti i maa ṣiṣẹ ki awọn eniyan ba le ri wọn, awọn ti wọn n wá iyin eniyan ti wọn kò si ṣe iṣẹ́ wọn gẹgẹ bi fun Oluwa.

**Itara ṣe Dandan**

“Ohunkohun ti ẹnyin ba nṣe, ẹ mã fi tọkàntọkàn ṣe e, gẹgẹ bi fun Oluwa, ki si iṣe fun enia” (Kolosse 3:23). Njẹ o ti i ni in lọkan ri lati ṣe inu rere pataki fun eniyan kan ti iṣẹ rẹ̀ wú ọ lori ti o si bu ọla fún? Njẹ ki yoo gbà pé ki o ṣọra ki o si ṣe aápọn? Ẹ jẹ ki a gbagbe ẹni ti a n ṣiṣẹ fun; ẹ jẹ ki a mu ọkan kuro lara rẹ̀; dipo rẹ̀, jẹ ki a wo Kristi lori aga gẹgẹ bi ọga iṣẹ́. Ẹni naa ti awa n ṣiṣẹ fun jẹ́ Ẹni ti o fi Itẹ Rẹ̀ silẹ ni Ọrun ti O si fi ẹmi Rẹ̀ fun wa. Gẹgẹ bi Onigbagbọ́, Oun ni a n ṣiṣẹ fun nisisiyii. Boya iṣẹ́ wa ni lati kan iṣo mọgi, tita ọja fun awọn onibara ni ile itaja, akọwe ni ile-iṣẹ tabi gbigbẹ kòtò oju títì, Oluwa ni a n ṣiṣẹ fun. “Fi tọkàntọkàn ṣe e,” fun Un.

Njẹ o n rò pé a kò san owó ti o tọ́ fun ọ, tabi a kò mọ riri iṣẹ́ rẹ? Ranti pe “Ohun rere kohunrere ti olukuluku ba ṣe, on na ni yio si gbà pada lọdọ Oluwa” (Efesu 6:8). Boya asanwo-oṣiṣẹ miiran ni o n wò; bi o bá n ṣiṣẹ fun Johannu, o kò gbọdọ reti pe ki Billi wá sanwo fun ọ. Bi o ba n ṣe iṣẹ fun Oluwa, Oun ni ki o maa wò fun ère.

“Awọn ti o si ni oluwa onigbagbọ́, ki nwọn máṣe gàn wọn nitori arakunrin ni nwọn; ṣugbọn ki nwọn tubọ mã sin wọn” (1 Timoteu 6:2). Onigbagbọ́ kò gbọdọ jẹ anfaani ijẹkujẹ nitori pe oun n ṣiṣẹ fun Onigbagbọ́ bi oun. Arakunrin naa ki yoo fi ọwọ́ lile tabi agbára mu ni bi ẹlẹṣẹ ti le ṣe; ṣugbọn sibẹsibẹ oṣiṣẹ paapaa gbọdọ fẹ́ lati ṣe iṣẹ́ oju-owo ọjọ kọọkan fun Onigbagbọ́ gẹge bi oun yoo ti ṣe fun ẹlẹṣẹ ti o le, ti o si maa n bere pupọ lọwọ rẹ̀.

**Idọgba niwaju Ọlọrun**

Fun awọn ọga ni Bibeli sọ pe: “Oluwa ẹnyin tikara nyin si mbẹ li ọrun” (Efesu 6:9). Awọn gbolohun ọrọ yii jẹ́ ki ọga iṣẹ́ mọ̀ pé oun ati oṣiṣẹ oun jẹ́ iranṣẹ niwaju Ọlọrun. Kò si ojusaju eniyan lọdọ Rẹ̀. O n fẹ ki ọga ṣe oloootọ gẹgẹ bi O ṣe n fẹ ki iranṣẹṣe pẹlu. “Ẹnyin oluwa, ẹ ma fi eyiti o tọ́ ti o si dọgba fun awọn ọmọ-ọdọ nyin; ki ẹ si mọ̀ pe ẹnyin pẹlu ni Oluwa kan li ọrun” (Kolosse 4:1). Ọlọrun, Ẹni ti o gbọ́ igbe awọn ọmọ Heberu ẹrú ti o si gbà wọn kuro ni oko-ẹrú Egipti ṣi n gbọ́ igbe awọn ti a n ni lara. “Kiyesi i, ọ̀ya awọn alagbaṣe ti nwọn ti ṣe ikore oko yin, eyiti ẹ kò san nke rara, ati igbe awọn ti o ṣe ikore si ti wọ inu eti Oluwa awọn ọmọ-ogun” (Jakọbu 5:4). Ọlọrun n beere lọwọ awọn ọga iṣẹ́ lati san owó-ọ̀ya ti o tọ́ ki wọn si lo oṣiṣẹ wọn daradara, “laisi idayafoni,” eyi ni pe ki iṣe fun ọga ibi iṣẹ́ lati maa yọ paṣan lé awọn oṣiṣẹ nitori pe wọn wà labẹ agbára rẹ̀.

**Itẹriba fun Ofin**

“Ọlọrun ki iṣe Ọlọrun ohun rudurudu, ṣugbọn ti alafia” (1 Kọrinti 14:33). Fun ẹri, ẹ jẹ́ ki a wo ayika wa ki a si kiyesi iṣedeedee iṣẹ́ ọwọ́ Ọlọrun – oorun, oṣupa ati awọn irawọ, gẹgẹ bi apẹẹrẹ -- ki a si ri eto ohun gbogbo ti Ọlọrun I ṣe Olupilẹṣẹ rẹ̀. Ki o ba le ṣe e ṣe fun awọn eniyan lati gbé pọ̀ ni alaafia, o ṣe dandan ki a ni ofin tabi ofin iṣakoso ìwà. Ọlọrun ni o fi eto naa lelẹ bẹẹ, o si fi Ofin Rẹ̀ fun Mose ki Israẹli ba le mọ̀ bi wọn yoo ti ṣe akoso ara wọn ni Ilẹ Ileri. Titi di oni-oloni ni a si n yẹ́ ofin yii si gẹgẹ bi ipilẹ ofin ilẹ wa.

“Awọn alaṣẹ ti o si wà lati ọdọ Ọlọrun li a ti làna rẹ̀ wá” (Romu 13:1). Ofin ti awọn eniyan n ṣe fun akoso ati iwa yiyẹ jẹ́ didun inu Ọlọrun. Bi awa ba n pa wọn mọ́ kò si idi ti a fi ni lati bẹru ofin. Bi a ba kọ̀ lati pa ofin naa mọ́, ki iṣe awọn alaṣẹ nikan ni a ni i bẹru, ṣugbọn a ni i bẹru ẹri-ọkàn wa ati Ọlọrun pẹlu. Kò buyi kún Onigbagbọ́ lati ṣá ofin tì, i baa jẹ mọ́ ofin irinna fun aabo wa tabi ilana nipa iṣẹ́ ti a n ṣe. “Ẹnyin kò gbọdọ ṣaima tẹriba, ki iṣe nitoriti ibinu nikan, ṣugbọn nitori ẹri-ọkàn pẹlu” (Romu 13:5).

Nigba miiran ofin miiran maa n wọ iwe ofin ilẹ wa ti o tako ofin ti Ọlọrun. Irú awọn ofin bẹẹ ki i ṣe ofin tootọ, awọn Onigbagbọ́ gbọdọ sa gbogbo agbára wọn lati má jẹ ki iru ofin bẹẹ fi ẹsẹ̀ mulẹ. Daniẹli ni idojukọ ofin kan ti o sọ pe kò gbọdọ gbadura, ṣugbọn ó gbadura. Peteru sọ fun awọn alaṣẹ pe, “Awa kò gbọdọ má gbọ́ ti Ọlọrun ju ti enia lọ.” (Iṣe Awọn Apọsteli 5:29). Awọn Onigbagbọ́ gbọdọ ṣaapọn lati dibo ati ki wọn gbé ohun wọn soke lodi si awọn ofin ti kò tọna ati ofin ti o n fi idi iwa buburu bi ọti mimu ati tẹtẹ tita mulẹ. Bi awọn ofin wa ba jẹ́ eyi ti o tọna, gbogbo eniyan ti o mọ ẹtọ ni yoo maa bu ọla fun ofin wa, bẹẹ ni wọn yoo si maa san ohun “ti o tọ fun ẹni gbogbo: owo-ode fun ẹniti owo-ode iṣe tirẹ̀: owo-bode fun ẹniti owo-bode iṣe tirẹ̀, ẹ̀ru fun ẹniti ẹ̀ru iṣe tirẹ̀; ọlá fun ẹniti ọlá iṣe tirẹ̀” (Romu 13:7).

## AWỌN IBEERE

1 Sọ ọ̀na diẹ ti a gba n sọrọ odi si ẹkọ Ọlọrun.

2 Ki ni awọn nnkan wọnni ti oṣiṣẹ gbọdọ maa ranti nipa iwa rẹ̀ nibi iṣẹ́?

3 Bi o ba gba iṣẹ́ rẹ si eyi ti o n ṣe fun Ọlọrun, bawo ni o ṣe ni lati ṣe é?

4 Ki ni aṣẹ ti a pa fun awọn ti o ni ọga Onigbagbọ́?

5 Darukọ nnkan meji ti Ọlọrun beere lọwọọga ti o gba eniyan si iṣẹ́.

6 Iha wo ni Ọlọrun kọ si awọn alaṣẹ ati ofin ilu?

7 Sọ idi meji ti Onigbagbọ́ gbọdọ fi gbọran si ofin ilu.

8 Darukọ eniyan Ọlọrun kan ti o ṣaigbọran si ofin ti kò tọna kan, ki o si sọ idi ti o fi ṣe bẹẹ.